IROHIN IMOLE

IMỌLẸ( ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

?lo. 588 FRIDAY APRIL, 24 1964 (2D)

# Awọn Ọlọpa Ri'Oku Oyinbo Kan Ninu Okun

OKUN :- Gbogbo enia ti o duro ni wọn bẹrẹsi ṣe idaro abiyamọ nigbati nwọn ri Oku Oyinbo alawọ funfun kan ti iṣan Okun gbe wa si ori iyanrin ni ọsan ana ti gbogbo enia si duro ti nwọn nwo o.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na ba ranṣẹ si awọn Ọlọpa, ko si pẹ pupọ lẹhin eyi, nigbati awọn Ọlọpa de, nwọn ri Oku Oyinbo na.

Nigbati nwọn se akiyesi Oku Oyinbo na daada, nwọn ri wipe ko si aṣọ kankan ni ọrun rẹ a n ṣokoto awọtẹlẹ penpe kan ti o wọ si idi.

Nigbati nwọn yẹ ṣokoto na wo, nwọn ri orukọ kan ti nwọn kọ si ṣokoto na ti o ka bayi, "D. C. Martins" ṣugbọn ko si adirẹsi ibiti o ngbe nibẹ.

Awọn Ọlọa ti gbe Oku Oyinbo na lọ si Ile-iwosan Lakulaku fun ayẹwo nwọn si nwa ẹniti o ba mọ Oyinbo na.

ỌDẸSANYA SỌ PE :

# IPINNU ADAJỌ LODI SI IRONU ỌMỌ ENIA !

EKO:— Ọgbẹni M A Ọdẹsanya, ọkan ninu awọn agbẹjọro ti o ngbẹnuṣe fun awọn enia mẹfa ninu ẹjọ ti Apapọ Ijọba mba Oloye Ọbafemi Awolọwọ ṣe l'Eko nisisiyi sọ fun Ile ẹjọ gigajulọ na ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi pe, ipinnu adajọ lodi si ironu ọmọ enia, lati sọ pe ki Ọgbẹni Nwaobiala o lọ si ẹwọn lori ẹṣẹ tl ko ṣẹ.

Ọgbeni Ọdẹsanya ṣe alaye f u n ile ẹjọ pe ọgbẹn Nwaobiala ko jẹbi ẹsun ti adajọ ṣ e idajọ ẹwọn rẹ si, o si ṣe ọpọlọpọ alaye lati inu iwe akọsilẹ ẹjọ ti Olujẹjọ na ro niwaju adajọ.

O tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe. bi ọgbẹni Nwaobiala ti ṣe de lati Ghana ni o ti lọ si Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti o si mba iṣẹ rẹ lọ.

Ṣugbọn ki o to sọ bayi t a n ni Ọlọla Adetokunbọ Ademọla bere pe, "Iru iṣẹ wo ni o lọ ṣe ni Ghana ti o fi pada si Ipinlẹ Ila Orun ?"

Ọdẹsanya: "Nwọn lọ kọ iṣẹ kan ni ọhun ni, ọjọ mẹta pere ni nwọn si ṣe ni Ghana, nwọn kan fi iṣẹ na pa owọ ni nwọn ko mọ nipa iṣẹ na, kini ọjọ mẹta to ṣe lati kọ iṣẹ tabi iru iṣẹ wo ni enia le fi ọjọ mẹta pere kọ ?"

Ademola: "Nwaobiala sọ fun ọ pe ẹlẹda on lodi si iru iṣẹ na?"

Ọdẹsanya: "Ko b a ni sọ ohun ti o jọ bayi, oluwa mi, nko s i ro

bẹ polu; ṣugbọn ti mo mọ wipe, b i o ti d e lati, Ghana ni o pada si Enugun lati ma a ba iṣẹ rẹ lọ"



Oloye O. Awolọwọ

Ademọla: "Ti ko ba ṣe iṣẹ rẹ kini o tun fẹ ki o se?"

Ọdẹsanya: "Mo lero pe ko duro ki enikan ṣẹṣẹ ma a paṣẹ fun on lati ṣ e ohun ti o t ọ ti o si y ẹ fun un lati ṣe k i o to m a a ṣe wọn"

Adajọ Agba ni on ri o si kọ awọn ọrọ kan silẹ ninu iwe ti o wa lori tabili niwaju rẹ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya ṣe ọpọlọpọ alaye, lori ẹjọ ti adajọ da ati ẹjọ ti o wa niwaju adajọ bi idajọ ti ṣe yatọ si ẹjọ ti nwọn ro silẹ.

O wa pe a k i y e s i Ijoko Igbimọ a w ọ n adajọ na si awọn ẹjọ ti adajọ kan da ni Eko ninu ọdun 1959, lori iru esun bayi na, o si ṣe afikun ninu ọrọ rẹ pe. Ipinnu adajọ lodi si ironu ọmọ enia, bẹni ko si faramọ akọsilẹ ofin.

Lẹhin ti Ọ g b ẹ n i Odẹsanya pari ọrọ rẹ tan lori ẹjọ kotẹmilorun Ọgbẹni Nwaobiala ni o wa bọ si ori ẹjọ ti Ọgbẹni Umọren.

Onirohin wa Ejọ'ngboro ti o lọ si inu ile ẹjọ na fi ye wa pe ọjọ na jẹ ọjọ "ibere" fun Ọgbeni Ọdẹsanya nitoripe bi o ti nsọrọ ni awọn adajọ mbere ọrọ lọwọ rẹ.

Bi nwọn si ti mbere ọrọ wọnyi, ni Ọgbẹni Ọdẹsanya nṣe alaye, o si tun nṣi iwe ofin lati fi gbe awọn alaye rẹ lẹsẹ.

Ọgbẹni Ọdẹsanya sọrọ fun Odidi wakati mẹrin ati abọ lori idu-

Wo Oju Ewe Kẹfa

# BARIKA — DE — SALLAH !



Aworan oke yi ni ti awọn Musulumi ti nwọn lọ jọsin ni Ọbalende l'Eko ninu ọdun Ileya ti o kọja yi.

Wo oju ewe kẹfa fun aworan ti Ebute-Metta.

# Ọgbọn Ati Ifi Oju Agba Wo Nkan Larin Yoruba

**Lati Ọwọ S. O. Jaiye, Eko**

Ọrọ to yẹ ki a fi oju agba wo larin Ilẹ Yoruba lode oni yi jẹ ọrọ akiyesi pataki ti mọ mu wa si iranti olugbe ilẹ Yoruba. Ṣaju pẹlu irẹlẹ ọkan ni mo fi mu ọrọ yi wa si arin wa. Inu mi yio dun pupọ ti awọn onkawe yi ba le kaa, ki nwọn si fi ọrọ ati itan diẹ ti mo fi ṣe omitoro ọrọ yi kọ ẹkọ, yio si jẹ ohun ayọ pupọ fun mi ti awọn ọba wa, oloye wa awọn Obinrin ati Ọkunrin Ọdọmọde ati ogo wẹrẹ ba le fi ara balẹ ka iwe yi pẹlu ọkan to gboro to si fẹ fun ironu ọgbọn ati oye.

Gbogbo wa ni ndara wa lẹjọ loni yi ti a si nfi ẹsun ole, irọ ati eke sun ara wa lojojumọ. Bẹni ko si irọ ninu rẹ.

BABA OLE

Itan kekere kan lọ bayi pe, baba kan wa, o jẹ ẹniti o ma nṣe afi ọwọ ra tali o saba ma njale ṣugbọn ko si ẹniti o ri mu rara. O wa di ọjọ kan Baba yi gbe agbada nla rẹ wọ.

Apo nla kan wa ninu ẹwu nla yi Bayi ni Baba na wa bọ si kọrọ kan nibiti awọn Ọmọde nsere.

Baba yi wa nsọ awọn Ọmọde wọnyi nitori adiẹ kan wa nitosi ti Baba yi fẹ ṣagabu tabi to fẹ ji gbe lọ.

Bi o ti bẹrẹ to gbe adiẹ yi sinu apo ẹwu rẹ Baba yi ko mọ pe Ọmọ kekere kan ninu awọn Ọmọde wọnyi nwo on.

Bi o ti fẹrẹ ma lọ ni Ọmọde yi kigbe pe "ole ole !! ole !!! " Gbogbo awọn yio ku ba nkigbe ole e e ! .

Bayi ni Baba agbalagba yi tẹsẹ mọ rin ti o si nlọ kọkan ṣugbọn Ọmọde wọnyi ko ye tẹlẹ ti nwọn si nkigbe si pe "ole ee !!! "

Nigbati o ya ni babaĩ yi ba fi ẹsẹ fẹ ẹ ti o si nsare lọ kọkan. Ko pẹ ni alagba kan pade awọn to nkigbe ole! ole!! ole!!!. Alagba yi tun bẹrẹ si sare lẹhin baba ole yi.

O ti bẹrẹ si rẹ bakanna awọn ọmọde ti nle e bọ wa arẹ mu wọn. Alagba yi ya nwọn silẹ ko pẹ o l e baba ole yi ba.

Ṣugbọn ọna awọn ọmọde wọnyi jina rere. Nigbati o mu ole yi dani. Baba ole yi wa dahun wipe mo gbọ pe o mu mi lọwọ. Ṣugbọn alagba jọwọ emi yo jọwọ ara mi fun nyin fun ayẹwo apo mi.

Jọwọ mo bẹ nyin pupọ wipe bi iwọ yo ba wa apo mi yi jọwọ fi oju agba ati oju aidojuti ni wo, Bayi ni o sọ ki o to jọwọ apo rẹ fun ayẹwo.

OJU ADIẸ

Bi o ti ya ẹnu apo rẹ fun alagba yi lati wo. bẹni alagba yi ri oju adiẹ to sa tabi to sa na waiwai ninu apo baba, Gẹgẹbi ọrọ ti baba ole yi ti sọ fun ẹbẹ pe ki o fi oju agba wọ ọrọ na,

Alagba ti ko fẹ dojuti baba ole yi lọgan o yi pada pade awọn ọmọde wọnyi wipe pada sẹhin ko si ohun kan ninu apo yi, Pada ẹnyin ọmọ buburu wọnyi.

Lọgan pẹlu irẹlẹ ọkan ni baba ole yi fi itẹriba dupẹ lọwọ alagba na ti o si gba ọna rẹ lọ gẹgẹbi ẹniti o ni idalare fun iwa ibi ti o nhu

Larin gbogbo ilẹ wa loni tani ko mọ pe ohun pupọ lo yingin ? Tani ko mọ pe iwa ibajẹ ti wọ ọpọ awọn asaju wa lẹwu fun aṣina owo Ijọba wa fun aibikita fun iwa ododo,

Ti a m o k u n ninu iwa ibajẹ bi ẹni mokun ninu omi nla, Bi awọn nkan wọnyi ti nṣẹlẹ ni awọn ọmọde nke ti awọn agba na nnaga wo awọn nkan wọnyi to ṣẹlẹ

Ti awọn oluṣe buburu nṣare kiri ilu nla, ileto ti nwọn tun gbiyanju lati sọ fun awọn olugbe ilu wọnyi pe ọna ti awọn nrin lọ dara ti nwọn tun sọ fun ni pe ọna ti nwọn lo mọ julọ.

OJU KOKORO

Gẹgẹ bi ẹda awa ko wipe ọna ẹnikan ko mọ.



Ọgbẹni S. O. Jaiye

A ko si wipe ọna awọn ko tọ rara.

A ko si sọ pe wọn ki gbe ọmọ adiẹ sere ninu apo nwọn.

Ti gboogbo awọn iwa sitọ nwọyi ti han si wa ni awa mọ. ko si ẹkun ile na ni Naijiria ti ẹnikan ki wa onjẹ ọjọ rẹ kiri pẹlu ilagun lojọ.

Ṣugbọn ebi ẹkun ile kan pọ ju ibomiran lọ pupọ fun ojukokoro ati ki a ma fi ẹmi ẹni wa ewo ki a ma gbe ọmọ ẹni fun ati ri owo lo.

Ati ki a fi ọmọ ọlọmọ gun ọsẹ awure fun owo, Mo ni nkan wọnyi buru pupọ bayi laiye atijọ Ọba ilu lo nri si ti o si fi opin si gbogbo iwa buburu bayi.

PANṢAGA

Opin ọrọ mi yi ni pe mo kesi awọn alaṣe Ile Yoruba ki nwọn fi oju agba wo ibajẹ ilẹ wa.

Mo kesi awọn akọni Obinrin ilu Ilẹ Yoruba ki nwọn fi oju agba wo ile yi,

Bẹni mo pe awọn ọjọgbọn ki nwọn sori kodo ki nwọn fi oju agba wo nkan wọnyi ki a ko wo jo fun imuti para, irede oru ni oju ọdọ ilu, bẹni iwa pansaga jẹ oju kan ti awọn ọdọ fi nwo aiye yi.

Ṣugbọn oju agba ni oju atunṣe ilu eyi to mọ daju pe on yo fi silẹ fun awọn Ọmọ nwọn lẹhin ọla. Fun idi eyi ẹjẹ ki gbogbo wa fi oju agbawo ọrọ atunṣe ile Yoruba.

Iba mi fun gbogbo ẹyin oluṣe rere.

Odigba o.


## Congreves Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin ti be ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabu ni ẹkọọkan ẹhin-didun, Ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹduda ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugbi Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn. ẹfọr abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gegebi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

**Ammoniated Quinine Tincture**

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# IWE SI OLOTU

## Mo Dupẹ Lọwọ Ejon'gboro

Ẹ dakun ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin Oloyin momọ to njade lojojumọ lati dupẹ lọwọ Ọgbẹni Ejongboro fun akitiyan rẹ lati ma ka irohin ẹjọ Kotẹmilọru Oloye Ọbafẹ A wolọwọ ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ.

Eyiti a ba fi mọ ka irohin na ni ọjọ keji gẹgẹbi atẹhinwa, ko ri bẹ mọ, bi awọn ti nka ede Oyinbo ti nka ede Oyinbo b na ni awa ti a mọ Yoruba ka ni a nka Irohin na ni ede Yoruba.

Awọn Olorin a ma kọ orin kan bayi pe, "enia lo le san lada, Ọlọrun ni o le san lada" nitiona fi Ọlọrun nikan ni o le san lada fun Ọgbẹni wa Ejongboro fun iṣẹ ti o nṣe,

Itan aladun, irohin nigbagbo-ẹniti nwukọ, ẹniti o yiomu gbogbo rẹ ni Ọgbẹni Ejongboro ni ti o si nfi sinu Irohin Imọlẹ fun wa ka.

Atata iṣẹ ni Ọgbẹni Ejongoro nṣe awa ti nka Irohin Imọlẹ Ọlọrun yio ran ọ lọwọ.

Olotu, ẹ ṣe pupọ fun aye ti ẹ gba mi. Ajinde ara yio ma je. Amin.

Emi ni,
Samuel Ojo

OSHOGBO.

## Musulumi Ki Iṣe Ẹyọ

Olotu

Nipa iwe mi, "Adajọ Coker ẹ ku ipalẹmọ" ti ẹ ṣe apọnle mi tẹ jade ninu iwe nyin Irohin Imọlẹ ti ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu kẹrin odun yi, ogunlọgọ awọn onkawe gbajumọ nyin ni nwọn ti nkansara si mi



Alhaji Y. A. Disu

titi di onioloni.

Nko mọ tẹlẹ pe, iwe na gbajumọ bi Isana ẸLẸẸTA mo fẹ lati fi iwe mi jẹ anfani iwe nyin nipasẹ ẸYỌ na. Ẹ jọwọ, ẹ gba mi laye die o A dupẹ o

Mo fẹ ki awọn onkawe nyin na mọ yekeyeke pe, ko tọ suna a ni o lodi si ẹsin Islam patapata porongodo fun musulumi lati ṣe ere ẸYỌ

Ẹni ti o ba ri nṣe ri, ki o ye ṣee mọ Ẹni ti ko ba ṣe e ri, ki o ma ṣe ṣe e, rara o.

Emi ni
Hadji Y. A. Disu

EKO

## A Dupẹ o Olotu

Olotu

Awa enia to ngbe Mushin dupẹ pupọ lọwọ nyin ati awọn osiṣẹ nyin fun iwe nyin oloyinmọmọ 'Irohin Imọlẹ' ti a si tete nri ka ni ilu Mushin nigba gbogbo.

Inu wa yio dun bi ẹ ba le ran wa lọwọ bi iwe na ba le pọ ju gẹgẹbi bi o ti wa tẹlẹ ri ki awọn ọpọlọpọ enia le ma rira ni ilu Mushin ati pe iwe na ki p tan ti a ba bere lọwọ awọn ti nta iwe irohin, nwọn yio sọ fun wa pe o ti tan.

Inu wa yio dun pupọ bi pupọ bi ẹ ba le ṣe iranlọwọ eyi fun wa, Iṣẹ nyin yio ma ni ilọsiwaju amin.

Emi ni
Laitan Omisande

MUSHIN

## Esiẹ Nfẹ Omi Ẹrọ

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu ba le gba mi laye diẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki nwọn ran wa lọwọ lati ba wa tun ilu wa ṣe o ti to ọjọ mẹta ti a ti nkesi Ijọba rere na ṣugbọn eti ikun ni wọn kọ si ẹbẹ wa.

Ilu Esiẹ nfẹ ẹrọ omi ti ao mọ mu nitori arun, gẹgẹbi awọn olofin imọtoto ti nsọ fun wa ni gbogbo igba pe, a gbọdọ ma mu omi ti o dara fun ilera ara wa

Omi ti a nmu ko dara wahala ti a nse ki a to ri omi mu ti pọ ju o nto ibusọ melokan ki a to ri omi pọn,

Ilu Esiẹ tun nfẹ oju ọna ọlọda ti awọn mọto wa yio mẹrin ti ekuru ko tun ni mọ ba aṣọ wa jẹ mọ ni asiko erun, ti atata ko ni mọ ba nsọ wa jẹ mọ ni asiko ojo

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o

Emi ni
Z. A. Ọmọniyi

ESIẸ

## Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ


# Gbanjo o !

Eyi ni latı kede fun gbogbo awn ONIBARA wa jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tete bẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

ỌJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 28th MAR.–30th APR

| | | | |
|---|---|---|---|
| Iwe Egogi Ajẹbidan | 25/— | | 22/6 |
| Iwe Ilana Ifa, Iyanrin titẹ Etutu ṣiṣei | 21/- | di | 18 |
| Iwe Afọsẹ Isẹdalẹ Yoruba Psalm Isẹgun Ajẹ | 4/6 | di | 3/- |
| Iwe Ala Nla | 7/6d | di | 5/6d |
| Iwe Ala ati Iwadi Nkan | 2/6- | di | 2/- |
| Turari Isẹgun Ajẹ | 10/6 | di | 8/- |
| Certificate of Appreticeship | 7/6d | di | 5/- |
| Tailor's Measurement Book | 7/6d | di | 5/6d |
| Iwe Itan Ala | 2/6d | di | 1/- |
| Iwe Itumọ Ami Ara | 4/6d | di | 3/- |

AKIYESI:— Enikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**
N2/99 Shittu Street
Ibadan



# EGBOGI JẸDIJẸDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu, pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupoju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni, tabi ti nrin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egboogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ ki o si danwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹd patapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogid taa igboro ilu Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

DEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street Yaba — Lagos

# Njẹ Ajẹ Mbẹ L'aiye?

Lati Ọwọ Alhadji Y. A. DISU

MO wolẹ, mo si foribalẹ fun Ọlọrun, mo si tọrọ lọwọ Ọba na pe ki o fi mi mọna. Mo tọrọ gaafara lọdọ iya ati baba mi. Mo tọrọ gafara lọdọ awọn iya ati lọdọ awọn baba ti nwọn gbọnju-gbọnlẹhin Mo si juba nyin. Ẹ jọwọ, ẹ jẹ ki iba fo mi o, ki nto bẹrẹ lati fi esi si ibere ti o wa loke iwe yi.

Ajẹ mbe laisi ani ani. Awọn tani Ajẹ? Awọn ti ọdaja enia bi tabi awọn ẹni ti ika eniaba bi. Tabi awọn ọmọ alapa kan. Awọn ajẹ ni pogun pupọ. Ofẹrẹ to ti Arọni ẹlẹsẹ kan Nwọn si ni agbara pupọ. Nwọn a ma a sọ "Oke d' ilẹ" Nwọn a si ma a sọ "Ilẹ di oke" Idi kan pataki niyi ti a fi gbọdọ sọ ara wa dada lori ilẹ aiye. Idi kan niyi pataki ti a fi ni lati sọ ara wa, ahọn wa, irio wa ati ijoko wa lọdọ ọmọ araiye. Oluwa Ọba awọn Ọba, afi ọla Rẹ bẹ Ẹ, da aabo Rẹ bo wa o. Idi kan niyi pataki ti a fi ni lati ma a gbadura ni gbogbo-igba.

Ọmọ ajẹ tabi ọmọ alapakan i ma a ko ọmọogun sẹhin, a ma a tan wọn danu lati fi da ile ru. A maa sọ botoboto.

A si ma a purọ yika ile ati adugbo fi da ile ati adugbo ru. "Baba rigimọ" ni oye alapakan. "Iya rigimọ" ni oye alapakan. O si le ba igbesi aiye ọmọ-enia jẹ patapata.

Ajẹ n iran mla a ntọju Ọmọ rẹ dada, o si ma a fun ni owo Ju gbogbo'rẹ lọ, ẹni ba nṣe dada ti o si ngba adura ni igbagbogbo yio ri a abo Edumare Ṣugbọn adura wa ko le gba, a fi ki a ni igbagbọ si Oluwa pe adura na yio gba Ki Ọlọrun gba adura wa, laiyembi ati l'ọrun. Amin o Ẹ jẹ ki a ma a bẹ Ọlọrun ki O ma a ba wa tu awọn eleṣu ti o nda ina irọ ka.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Orişirişi işoro yio şelẹ si ọ loni, şugbọn pẹlu suru ati isgiu, awọn yio bo ọrọ ogun yio da ija silẹ.

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Maşe lora lati mu ero ọkan rẹ şẹ ọna irọrun ti o le gba şẹ e mbẹ niwaju, Ija yio bẹ silẹ larin iwọ ati aladugbo rẹ kan, mu suru.

ARIES (Mar 21 - April 20) Ẹmi ara rẹ ibe ninu ewu, nitorina şọra ki nwọn ma ba şe ọ ni jamba nibi iran wiwo, ki o ni iforiti, yara san gbese owo kan ti o ti jẹ, ma kiyesi ara rẹ.

TAURUS (Apl 21 - May 20) Gbogbo ohun ti o ba dawọle loni, ire ni yio jasi, fẹran gbogbo awọn to nifẹ rẹ lọkan, ẹnikan nreti iranlọwọ rẹ nisisiyi.

GEMINI (May 21 - June 21) Maşe jẹki irẹwẹsi sọwọ rẹ delẹ, tabi ki irẹwẹsi gbe ọ lọ jẹki ọkan rẹ şe ọna kan, ko fetisi ọrọ ti nwọn ba ba ọ sọ, Şe pẹlẹpẹlẹ.

CANCER (Jun 22 - July 23) Maşe jafara lati gbọ ti ara rẹ ki o si gba ọgbọn ti nwọn ba fi kọ ọ. Maşe jẹki arẹ mu ọ, onjẹ adidun ni ki o jẹ sun loni.

LEO (July 24 - Aug. 22) Irawọ rẹ ti tan, maşe jafara lati şe gbogbo ohun ti o ngbero lọkan lati şe, Maşe gbagbe awọn ara ati ẹbi rẹ, maşe jaiye ajẹju.

VIRGO. (Agu 23-Sep 23) Iwọ yio gbọ irohin alayọ loni, jẹki awọn enia ti ọ lẹhin, maşe gbagbe ohun ti o nşe lojojumọ, maşe ba ẹni kan ja, jẹki gbogbo ohun ti o ba fẹ şe di ẹhin ti o ba ti jẹ onjẹ alẹ tan.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Ohun ti o gbero lọkan lati şe yio jẹ re. Maşe şe okan tulasi, ọjọ oni dara lati pari ija, iwa jẹjẹ ati iwa irẹlẹ to dara fun ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 25) Işẹ rẹ toni dabi eyiti o fẹrẹ bi ọ ninu, bi o ba si jẹbẹ, ọgbọn ati suru ni ki o fi yanju rẹ, obinrin kan yio fi ife han ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 23) Ọgbọn ori rẹ ni yio lana fun ọ loni. Ika yio sunwọn fun ọ lalẹ oni maşe pe lori ẹni.

CAPRICORN (Dec 24-Jan. 21) Işọra di ọ wọ rẹ bobajẹ pe, awọn ọwọ rẹ nrao gbe, maşe dalẹ nşe ni ki o ma şe ikilọ fun wọn ki ija ma bẹ silẹ.


## Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Pupọ rinu awọn egbogi rọbirọbi ti wọn npolowo ti wọn si nta kakia igoroiju Eko ati ni igbereko ko ni şe iwsan wọn lailai afi ki o ri ojulowo haunhaun atamase egbogi ti o lagbara gidigidi ti o le şe iwosan rẹ titi de inu ifun ati igb-aya ti yio mu ọ ma tu "Ikọ" mọ bi kẹlẹkẹ jade ti o ba rhu ẹ titi yio fi tan ni inu rẹ qatabata. Awọn ikọ miran wa ti o dabi ẹnipe wọn ama la ogun tabi orişirişi egbogi tabi ti o ba jẹ pe beni, agba ọ ni imoran wipe ki o ma lo egbogi awon ara ilu Abyssinia ti nwọn npe ni "Etibard" pẹlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki nia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana ati loru-gbiyanu lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara idigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi şorokiti ti wọn nta kakiri

O daju nibe iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma ẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn Bere egbogi ajẹbina yi ni şọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8 Plamchurch Street, Lagos
Phone:-22878 ,Nigeria, (Ọja ita Faji)



AH! REMEMBER THAT

## The Social Dandies

*PRESENTS*

### An id-Ul-Kabir Dance

AT

FORESTER CENTERY HALL

22, Ọdunlami Street, Lagos. On Sunday 26th Apri 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

### Tickets: 4/- Flat

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboşe Street, Irohin Imolẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.

O ku ọjọ mẹrin loni.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORẸ AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 588 FRIDAY, APRIL 24, 1964 (2D)


## Awọn Ọmọ Ẹgbẹ Akọrin Binu Jade Ninu Ṣọọṣi

FREETOWN:- Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkandinlogun oṣu yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ akọrin Ijọ "Saint John's Anglican" Sierra — Leone ba binu jade nigbati nwọn nṣe isin lọwọ, ti gbogbo wọn si lọ binu bọ aṣọ ọrun wọn silẹ.

Oniwe Irohin wa ni Freetown fi yi wa wipe, edeaiyede kan wa larin oniwaṣu Ijọ na ati Olori awọn akọrin ti o ntẹ duru fun Ijọ na.

Awọn ọmọ Ijọ si da si ọrọ na lati pari rẹ fun wọn, ṣugbọn oniwa nbinu si iwa ti aluduru na hu pe ko dara to rara.

Lẹhin aṣaro pẹlu awọn Igbimọ Ijọ gbogbo wọn pa ẹnu pọ pe, ki nwọn yọ aluduru na, ki nwọn si gba ẹlomiran ropo rẹ.

Gbogbo igbati nwọn ṣe eto yi awọn ọmọ ẹgbẹ akọrin ko gbọ, titi ti oniwasu Ijọ na fi fun aluduru na ni iwe pe ki o maṣe wa si ṣọọṣi, ki o fi iṣe rẹ silẹ.

Nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ akọrin de Ṣọọṣi ti nwọn rẹti aluduru wọn titi ti nwọn ko ri, ki nwọn to bẹrẹ isin, nigbati nwọn nṣe isin lọwọ ti nwọn gbọ ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ akọrin na ba binu jade, nwọn bọ aṣọ wọn silẹ ni wọn ba lọ si Ile wọn.

Oniwe Irohin nwadi iru ẹṣẹ ti ọkunrin na ṣe ti nwọn fi yọ ọ kuro ninu ijọ

# ẸGBẸ ALAKUKỌ YỌ LAMUYE KURO L'ẸGBẸ

EKO:— Ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi ni Igbimọ Amuṣe ẹgbẹ Alakukọ fun Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe ikede fun gbogbo aiye gbọ lẹhin ipade pajawiri kan ti nwọn ṣe wipe, Igbimọ ẹgbẹ na yọ ọmọ-Ọba T. A. Lamuye, ti iṣe akọwe labẹ Minista Alamojuto Eto inawo fun Apapọ Ijọba Naijiria kuro ninu ẹgbẹ.

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ fun oniwe irohin wa pe, ipinnu na ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe lẹhin ipade ti awọn ṣe ninu Ile Igbimọ awọn agba Oṣelu fun Apapọ Ijọba Naijiria.

Agbọrọsọ na tun ṣe alaye fun Ejo'ngboro pe, ọmọ Ọba Lamuye ti nhuwa gbelẹgbida lọna ẹburu si ilọsiwaju ati iṣọkan ohun idagbasoke ẹgbẹ ni Orilẹ-ede yi, paapajulọ ninu ilu rẹ ti iṣe Iwo.

Agbọrọsọ na wa ṣe alaye pe, lẹhin ti awọn ti yọ kuro ninu ẹgbẹ yi, ọmọ-Ọba na yio padanu aye rẹ ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba gẹgẹbi akọwe labẹ Minista eto inawo.

Bakanna ni ẹgbẹ na sọ ninu ikede kan ti o jade l'Eko pe, ọmọ Ọba Lamuye yio tun padanu aye majẹobajẹ ti o wa ninu Ile Igbimọ na, nitori "iwa Agbelẹgbida" ti nwọn sọ pe o nhu labẹlẹ.

Ṣugbọn nigbati oniwe irohin wa ni Iwo lọ si ọdọ ọmọ-Ọba Lamuye, o ṣe alaye pe, o jẹ ohun ti o ya ou lẹnu nigbati on gbọ ọrọ na lori ẹrọ -asọrọmagbesi wipe awọn ọmọ ẹgbẹ on yọ on kuro ni ẹgbẹ.

O tun ṣe alaye pẹlu iyanu wipe, Igbimọ Amuṣẹṣe ẹgbẹ Alakukọ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti tuka nigbati edeaiyede kan ti de larin wọn, ni nwọn ti tu Igbimọ na ka.

O wa bere pe, "Ẹgbẹ ti a ti tuka nitori aiṣedeede wọn bawo ni ẹgbẹ na ṣe le tun ni aṣẹ lati yọ ọmọ ẹgbẹ kan nigbati nwọn ko ti tun awọn ọmọ ẹgbẹ na to?"

Oniwe Irohin wa, Ejo'ngboro wa Oloye Olu. Akinfosile ti iṣe Alaga Igbimọ ẹgbẹ na de ile ni irọlẹ ana, ṣugbọn ko ba lati gbọ ọrọ ẹnu rẹ.

Ṣugbọn ọmọ Ọba Lamuye ṣe alaye fun oniwe Irohin wa pe, bi ẹgbẹ kan ba fi ẹsun kan ọmọ ẹgbẹ rẹ, nwọn gbọdọ gbọ ti ẹnu ọmọ ẹgbẹ na ki nwọn to le yọ oluwarẹ kuro ninu ẹgbẹ.

## Ipinnu Adajọ Lodi Si Ipinnu Ọmọ Enia!

Lati Oju Ewe Kini

ro, gbogbo awọn ibere ti awọn adajọ ba si bere lọwọ rẹ ni o nda wọn lohun.

Eyi ni o si di ọjọ kẹjọ ti nwọn ti bẹrẹsi ro ẹjọ na. Awọn enia mẹtala pere lo nwa si Ile-ẹjọ na ninu awọn olujẹjọ na lati ọjọ ti ẹjọ na ti bẹrẹ.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ funrarẹ ko wa si ile ẹjọ ati Ọgbẹni Samuel Onitiri Ninu awọn enia ti o nwa si Ile ẹjọ na ni Ọgbẹni Latifu Jakande ati Ọgbẹni J. S. Ọlawẹyin.

Ijoko awọn adajọ na gba isinmi Ọdun Ileya, oniwe Irohin wa Ejo'ngboro fi ye wa pe, Ile ẹjọ na yio ṣe ẹjọ ni owurọ yi, ṣugbọn ki iṣe ẹjọ ti Oloye Awolọwọ, ẹjọ tirẹ tun di ọjọ mẹrin loni, ṣugbọn eo tun ma gbọ iyoku ọrọ ti Ọdẹsanya sọ ninu iwe wa ọla



Aworan oke yi ni ti awọn Musulumi ti nwọn lọ josin ni Row Park ni Ebute-Metta ninu ọdun Ileya to kọja yi.


Printed and Published by Mọfope Printing Press 16, Pangbose Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEKOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 24/4/64